## AWỌN Ọ̀RẸ́ RERE MEJI

**1 Samuẹli 14:1-16; 18:1-4; 20:42; 23:16-18; 2 Samuẹli 1:17-27.**

**Ẹ̀KỌ́ ARỌ́PÒ**

**AKỌSORI: "Ifẹ ki iṣe ohun buburu si ọmọnikeji rẹ" (Romu 13:10).**

Lonii a o kọ́ nipa ọdọmọkunrin arẹwà kan ti i ṣe ọmọ-ọba. Baba rẹ̀ ni ọba gbogbo awọn eniyan Ọlọrun ni Ilẹ Mimọ́. Orukọ ọmọ-ọba naa ni Jonatani, ó jẹ́ ọmọ rere, ó si gbọ́ràn. Jonatani fẹran baba rẹ̀ ati gbogbo awọn eniyan Ọlọrun. Nigba ti awọn keferi, ti wọ́n n sin oriṣa dipo Ọlọrun otitọ wá mú ipalara bá awọn Ọmọ Israẹli, Jonatani ran baba rẹ̀ lọwọ lati lé wọn lọ.

Nigba miiran awọn Filistini wá, wọ́n si pàgọ́ si afonifoji ni odikeji ibudo awọn Ọmọ Israẹli. Awọn Filistini ni agbára, wọ́n si pọ̀, awọn Ọmọ Israẹli kò si mọ ohun ti wọn yoo ṣe. Ni akoko yii, Ọlọrun lo ọdọmọkunrin miiran ti ó fẹran Ọlọrun. Ó ti ri igbala, ó si maa n gbadura si Ọlọrun ni ojoojumọ, gẹgẹ bi a ti gbagbọ́ pé Jonatani maa n ṣe. Gbogbo wa ni a mọ ọmọkunrin yii - orukọ rẹ̀ ni Dafidi.

A ranti pé òmìrán nì, Goliati, a maa jade wá si afonifoji ni oroowurọ ati ni aṣaṣalẹ a si maa kigbe si awọn Ọmọ Israẹli lati rán ọmọ-ogun kan jade wá lati bá oun jà. Nigba ti Dafidi rí òmìrán yii, ti ó si gbọ́ bi ó ṣe n kigbe si awọn eniyan Ọlọrun, ó fẹ́ lọ bá Goliati jà. Ni akọkọ ọba sọ fun Dafidi pé kí ó má lọ; ọmọdekunrin ni kò si ni agbara tó lati bá Goliati omiran nì jà, ṣugbọn Dafidi sọ fun ọba pé Ọlọrun yoo ran oun lọwọ.

Dafidi mọ̀ pé Ọlọrun tobi, Ó si ní agbara ju gbogbo awọn omiran ti ó wà ninu ayé lọ. Ó sọ fun ọba pé nigba ti oun tọju agbo ẹran baba oun nitosi awọn oke, kiniun kan wá ó si gbé ọdọ-agutan kan kuro ninu agbo, ó tẹlé kiniun naa, ó gba ọdọ-agutan naa kuro ni ẹnu kiniun, ó si pa kiniun naa pẹlu ọwọ́ rẹ̀. Nigba miiran amọtẹkun kan wá lati gbé ọdọ-agutan, Ọlọrun si ran Dafidi lọwọ lati pa amọtẹkun naa, pẹlu.

Nigba naa ni ọba jẹ́ ki Dafidi lọ. O mú kannakanna ati apo oluṣọ-agutan rẹ̀, ó si ṣa okuta marun-un ti ó jọ̀lọ̀ bi ó ti n kọja nibi odò. Lai si aniani, Dafidi n gbadura bi o ti n yara lọ. Nigba ti ó sunmọ omiran naa, ó fi okuta sinu kannakanna rẹ̀, ó fì í yika ori rẹ̀, ó si jọwọ rẹ̀ lọwọ lọ. Ọlọrun mú ki okuta naa lọ sinu agbárí omiran naa, ó si ṣubu lulẹ̀!

Ọba tun fẹ bá Dafidi sọrọ lẹyin iṣẹgun nla yii. Lai si aniani Jonatani duro nitosi bi ọba ati Dafidi ti n sọrọ, Jonatani fẹran Dafidi pupọ. Boya ó tilẹ rò pé: Ọmọkunrin yii fẹran Ọlọrun gẹgẹ bi emi naa, mo si fẹ́ jẹ́ ki ó jẹ́ ọ̀rẹ́ mi. Ọba sọ fun Dafidi pé kí ó wá maa gbé pẹlu wọn, inu Jonatani si dùn. Jonatani ki i ṣe alani-kan-jọpọ́n; ó n fẹ́ ṣe ajọpin ile rẹ̀ daradara ati awọn nnkan ti ó ní pẹlu Dafidi. Ó bọ́ ẹ̀wù rẹ̀ ó si fi fun Dafidi, oun ati

Dafidi si ṣeleri pé awọn yoo maa jẹ́ ọ̀rẹ́ rere nigba gbogbo. Dafidi n gbé pẹlu ọba ati Jonatani, ó si n ràn wọ́n lọwọ lati jà nigba ti awọn ọ̀tá bá wá lati mú ipalara bá awọn eniyan Ọlọrun.

Awọn eniyan fẹran Dafidi nitori ó ṣe ìyọ́nú si wọn, ó si n ràn wọ́n lọwọ. Eyi mú ki ọba jowú. Ọba n fẹ́ ki awọn eniyan bu ọlá fun oun ki wọn si gbẹkẹ lé oun ju bi wọn ti lè ṣe fun ẹnikẹni lọ. Ó rò pé boya awọn eniyan yoo lé oun lọ, wọ́n a si fi Dafidi jọba. Njẹ iwọ kò rò pé ọba dabi awọn ọmọde miiran ti wọ́n saba maa n fẹ́ ipò kin-in-ni ti wọ́n si n fẹ́ nnkan ti ó dara jù fun ara wọn.

Boya Jonatani rò pé ni ọjọ́ kan oun funra oun yoo jẹ ọba, ṣugbọn nigba ti ó ri bi Dafidi ti dara tó ati bi ó ti n ran awọn eniyan lọwọ, ti awọn eniyan si fẹran rẹ̀, Jonatani kò bikita bi Dafidi tilẹ jọba. Ó fẹ́ ki awọn eniyan naa ni ọba rere, bi Dafidi bá si lè ran awọn eniyan naa lọwọ ju bi oun ti lè ṣe lọ, ó fẹ́ ki Dafidi jẹ́ ọba.

**IBEERE**

1. Ki ni ṣe ti Jonatani lọ si ibudo awọn ọ̀tá pẹlu onihamọra rẹ̀ nikanṣoṣo? 1 Samuẹli 14:6.
2. Ki ni Ọlọrun ṣe lati ran Jonatani ati onihamọra rẹ̀ lọwọ? 1 Samuẹli 14:15.
3. Bawo ni Jonatani ti fẹran Dafidi tó? 1 Samuẹli 18:1, 3.
4. Bawo ni a ṣe gbọdọ fẹran Ọlọrun ati awọn eniyan Rẹ̀ tó? Luku 10:27.
5. Ta ni fẹran wa lonii ju bi Jonatani paapaa ti fẹran Dafidi lọ? Galatia 2:20.